JIMO RAMONU LO SI EWON ODUN MARUN


# IROHIN YORUBA

Eşin Oro Wa— "IWAJU L'ỌPA ẸBITI NRE SI"


**Akiyesi**

Ti ẹ ba nkọwe si wa ki ẹ ma a kọ o yanju, ki a le tete ma a tẹ ẹ jade fun nyin, eyiti ko ba yanju dele kole jade rara. Nitorina a tun tẹ mọ nyin leti daradara "Ẹ ma kọ iwe nyin yanju o"

Olotu

ỌBA ONI SE IDUPE FUN ỌMỌ RE ; ADAJỌ SO OLOTU "SAOLA AGENCY" S'EWỌN


VOL, IV N 683 IBADAN, MONDAY, SEPTEMBER 17, 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA KỌBỌ KAN (1d)


## Adisa Ramonu Lo S'ewon

Ni Kotu Gaaran (Lagos Assize) ni ọjọ kẹfa oşu yi ni Adajọ agba Ogbẹni J. R. Cregg sọ Jimọ Adisa Ramọnu si ẹwọn ọdun marun onişẹ aşekara nitori ti o jẹbi ẹjọ apania ti Ijọba mba a şe.

Pataki ẹjọ ti Jimọ Adisa Ramọnu ro ni pe nigbati on nlọ gba egbogi ni Ile Iwosan (Hospital) on gbagbe iwe ti on o fi gba egbogi silẹ, bi on ti pada lati wa mu iwe na ni on ba ilẹkun iyara on ni titi, on pe iyawo on Musiratu Akankẹ, o si dahun ninu iyara, on si bere pe kini şe ti o fi ti ilẹkun mọri, o ni on nşe nkan. Kini o nşe? ko dahun mọ,

Nigbana ni on fi agbara şi ilẹkun, on si ri iyawo on lori ibusun ati ọkunrin kan ti o sa pamọ si abẹ ibusun, nigbati on si bere pe tani ẹniti o wa labẹ ibusun? iyawo on si dahun pe tani iwọ fi pamọ sibẹ? Şe titori iyẹn na ni o şe pada o si ti ri ohun ti o fẹ ri na, ki o tẹ ifẹ ọkan rẹ lọrun ni o ku.

O ni eyi ni o mu inu bi on lati yọ ada ti on si ṣa a pa pẹlu ọrẹ on Salami Jimọ ti on ba ni iyara pẹlu rẹ ti o nşe ale iyawo on na,

Lẹhin na ni Loya D. O Ibekwe ti nşe agbẹjẹro fun ọdaran na wa laa ye Adajọ ati awọn Igbimọ Kotu (Jury) pe bi o ba şe pe nigbati Ramọnu ba iyawo na ati Salami Jimọ ni iyara ki nwọn bẹ Ramọnu ni, on ki ba ti pa wọn nitorina ko ni ero apania ninu, ibinu ni o fa a

Nigbati awọn Juuri si wọ iyẹwu Kotu lọ lati lọ yẹ ẹjọ na wo, ipinnu ti awọn mu jade wa fun Adajọ ni pe Jimọ Adisa Ramọnu ko jẹbi amọmọ-pania (Murder) şugbọn o jẹbi aşeşi-pania (manslaughter). Nigbati Adajọ gbọ ipinnu awọn Juuri ni o ba ẹe idajọ gẹgẹ bi a ti sọ si oke yi,

Ni ọgbọnjọ oşu kẹfa ọdun yi ni gbogbo nkan wọnyi şẹlẹ ni Abule Atarọmi ni ọna Yaba. Ọjọ buruku eşu gbomi mu.

### KULUMBU L'ỌMỌ NA RI

ACCRA G.C—Laipẹ yi ni Ọlọrun fi ọmọ kunrin kan lantilanti jinki Ọgbẹni Yesufu Amale ati Sifawu Anikẹ aya rẹ. Nwọn si sọ orukọ ọmọ na ni Lamidi Oyedele.

Awọn ọmọ Ojo Alade'ji şe inawo ni ọpọlọpọ nibi ikomọ na, awọn baba ọmọ, Salami Akano, Samuel Adisa şe inawo pupọ, ki Oluwa da ọmọ na si ki o si fi ire kari gbogbo awọn alabaşe.



Dokita Akinola Maja

Baba Ẹgbẹ Apapọ Ẹgbẹ N. Y. M. ati ẹkan pataki Igi lẹhin ọgba fun Ẹgbẹ Afẹnifẹrere Action Group
Ẹ dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹrere (Action Group)

### A ŞE YI ŞAMỌDUN OJU A PE, ẸSẸ A PELE O.

AGỌ-IWOYE — Awọn Ijọ Methodist ni ilu Agọ Iwoye ati agbegbe rẹ şe Ajọdun kini ti wọn di ominira (Self Supporting Circuit) ni ọjọ kini ati ọjọ keji oşu yi (1st & 2nd Sept, 1951)

Ni agogo mẹwa owurọ ọjọ kini oşu na ni wọn şe Ipade nla kan labẹ akoso ọba Alaiyeluwa Fibigbade I Ebumewe Agọ Iwoye ti a si yan awọn Sanmori gbogbo lati jẹ Isongbe rẹ. Ọgbẹni S, Akin Oshuntoye, Alagba M, T, Okuwa, J, O. Onamade, M A Fagbamila Alufa J. O. G. Şodipẹ Alufa Ijọ C.M.S. Agọ Iwoye ati Alufa F, A. Ogunşẹyẹ Alufa Circuit na.

A ka irohin ni kikun lati ẹnu Alagba J. O. Onamade (Circuit Steward) ati Alufa E. A. Ogunşẹyẹ (Alufa Circuit) gẹgẹ bi işẹ ti lọ si lẹhin ti Ijọ yi di ominira. A si ri pe Circuit yi ni owo lọnito ati aniseku, Awọn ẹniti o si sọro ninu Ipade na ni Alagba S. A. Oshuntoye ati M T Okuwa Ohun ti wọn si tenu mọ lojo na ni lati ni ki wọn fun işẹ Olọrun yi ati lati ... ẹni ẹtito pẹlu ara wọn.

Lẹhin eyi ni Alufa J, O, G, Şodipẹ şe isin Iyasimimọ aşọ awọn Akorin Ijọ yi (Cusock & Sunlice) ki a to mu Ipade na wa si opin pẹlu adura.

Ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ keji ninu oşu kẹsan ninu ọdun yi, na ni wọn şe Isin ọpẹ pataki ti o larinrin ninu Ile Isin Methodist labẹ akoso Alufa D B Esan (Alabojuto Ijọ Methodist ti Abẹ-Okuta) ti Alufa Ijọ na E A Ogunşẹyẹ şe oluranlọwọ fun

Alufa D B Esan ni ẹniti o şe Iwasu Isin alarinrin yi

## Adajo So Olot "Saola Agency" S'ewon

Ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹjọ oşu yi ni Adajọ Kotu kini ti Saint Anna ju Ọgbẹni S Agbolade Ọlawoye, Oninkan ati Olotu ti "Saola Agency" ti 7 Agoro Court Lagos si ẹwọn oşu mẹsan fun ẹjọ ole ti awọn Ọlọpa baa şe.

Ẹsun ti awọn Ọlọpa fi sun ni pe o jale adọrin pọnun (£70) ti Ogbẹni Nat Makinde oni-Iwe Irohin l'Oshogbo san fun un lati inu oşu karun ọdun yi pe ki o san fun Alhaji Akande ti o ra moto lọwọ rẹ.

Nigbati Makinde si bere owo si pe ki o da a pada fun on, ko si da owo na pada.

O si sọ pe on ko feramọ Adajọ na, nitorina on a gbe ẹjọ on lọ si Kotu nla, şugbọn awọn Ọlọpa ko gba iduro rẹ.

## Ẹ Dibo Fun Egbẹ Afenifere Action Group

## Ọba Ọni Se Idupe fun Ọmọ Re

IFE- Ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kẹfa osu yi ni Oba Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi kinni K.B.E, C M G şe idupẹ pataki ni inu Ile Isin St Peter's, Irẹmo, Ifẹ fun ti ọmọ rẹ obinrin, Ọmọ-Ọba Tẹjumade Aderẹmi ti o ti ilu Oyinbo de ẹniti o ti lọ fun ẹkọ giga lati ọdun 1947.

Alufa Ijọ Cannon E.O. Ajibọla ni o şe eto Isin idupẹ na, awọn Alufa D.E. Ogunbanjọ ati R.A. Fajẹnisin ti Ijọ St Stephen's Modakẹkẹ ni o ran lọwọ ninu isin na.

Tinu-Tode Ile Isin na ni okun fun ọpọ enia. Alufa Ijọ na ni o si şe Iwasu pataki fun isin idupẹ na. O sọrọ iwuri pupọ nipa iwa Ọba Ọni ati bi o ti jẹ Ọba ti o ni ibẹru Ọlọrun lokan si ti o si ni ifẹ si gbogbo enia, O si tun yin ọmọ-ọba na fun akikanju ati ifarabalẹ rẹ lati le pari ẹkọ rẹ ni ilu Oyinbo pẹlu ẹkunrẹrẹ.

Lẹhin isin ni gbogbo Ijọ ati gbogbo enia ba ba Ọba lọ si ile o si fi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun fun ayọ ti ọmọ rẹ na.


Ẹ ma a ka iwe
**Irohin Yoruba**
alghagbogbofu urişirişi irohin


OWE : ỌGBỌ ỌGBỌN NI AGBALAGBA FI SA FUN MALU

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## MO DUPE LOWỌ AKANDE

Mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi lati sọrọ sinu iwe yi. Gbogbo awa ọn ọ Igbala a ko le ṣe alai dupẹ lọwọ Joseph Akande ni Ogbomọṣọ nipa ọrọ wọn ti o jade ninu Iwe Irohin 16:7:51 gẹgẹbi - Akewukewe kan tiṣe wa ka wọn mọle ti wọn si ṣẹgun rẹ, a dupẹ pupọ lọwọ Ọgbẹni na, nitoripe nigbagbogbo ni wọn ngbe orukọ Jesu ga. Ọlọrun ko ni jẹki okunkun bori imọlẹ, ki Ọlọrun mu akoko wa ti imọlẹ yio bori okunkun, ti awọn paapa yio fi mọ pe ko i oruko miran labẹ ọrun ti a fi le gba ni la, a fi oruko Jesu.

A si tun dupẹ lọwọ Alagba S Idowu ti Eko nipa alaye lori Aiye loja ọrun ni ile, ti wọn la ye wa kedere pe Ọrun ni ile fun ẹnikẹni, ki Jesu mu wa lọ si Ọrun alafia, lẹhinna a dupẹ lọwọ Joseph Akande, S Idowu Ajibinrere, Alice Jokotade, G O Okẹ, E O Martins, fun akitiyan wọn lati ma fi Iwe Irohin kede Igbala, nipa alaye wọn, a si ti ri ọpọlọpọ Imọlẹ, Awọn Imale paapa mọ pe Jesu ni Imọlẹ, afi ẹniti ko ba ni gba loku.

Emi ni
Joseph Taiwo

JOS.

## ONIGBAGBỌ (CHRISTIAN) Ẹ LA EYI YE MI

Ẹ jọwọ, ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe nyin a k ọ n i l ọ g b ọ n lati fi ibere mi yi siwaju awọn Ọgbẹni S. Idowu Ajibinrere Alagba Evangelist Akande Ogbomọṣọ ati Omidan Alice Jokotade Alawiye ati awọn Alufa (Pastors) ti nwọn nba wa ka Iwe Irohin Yoruba yi. Ati awọn ẹlomiran ti oye Bibeli Mimọ ye pẹlu.

Ibere kini:- Njẹ o yẹ ki alagbaṣe ti ṣe aborisa (Heathen) ki o lọ lati ṣiṣẹ ni oko Onigbagbọ (Christian) ni ọjọ isimi (Sunday) bi?

Ibere keji:- Njẹ o yẹ ki Onigbagbọ (Christian) ki o ma da owo fun awọn Imale (Muhammedans) nigbati nwọn ba fẹ kọ Mọṣalaṣi (Mosque) bi?

Ibere kẹta:- Njẹ o yẹ ki Onigbagbọ (Christian) ki o ma ra akara ṣe sara lọjọ Ẹti (Friday) bi?

Ibere kerin:- Bi O n i g b a g b ọ (Christian) ba fẹ ọmọ a b ọ r i ṣ a (Heathen) l'obirin ti ọmọ aborisa (Heathen) yi ko ba fẹ fi iwa ibọriṣa (idolatry) yi silẹ, o yẹ ki Onigbagbọ (Christian) na ki o kọ ọ silẹ ni tabi ki o ma kọ ọ silẹ?

Ẹ la eyi ye mi. Mo dupẹ o Olotu, ọkọ ọba ko ni ṣa yin l'ẹsẹ o amin. Iwaju ni ọpa ẹbiti yio ma re si o,

Emi ni,
Timothy Ayọọla Ojo

OGBOMỌṢỌ.

## Ẹ LA EYI YE NI

Olotu Iwe Irohin Yoruba, mo ki nyin pupọ, Ọlọrun Olodumare ko ma ṣọ nyin ninu ewu gbogbo, amin. Ẹ jọwọ ẹ dakun, mo fi Ọlọrun bẹ nyin, ẹ ran mi lọwọ nipa ibere mi yi, ẹ jẹki o tete jade, wọn baba wa ni ma pa lowe pe, "mbọ ni mbọ, awọn laarẹ silẹ de e" awọn si tun ni "Ẹnikan ko rẹ awọn silẹ ma, oju ni, wọn nmuto", toto o ṣe bi owe o.

Ibere mi na ni pe, Bibeli, ọrọ Ọlọrun Olodumare tiṣe de ori ọpọn awọn oniwosi-wosi lati ta, tabi lori igba awọn obinrin? Ti Bibeli fi di idiyele, ti a fi owo Bibeli ki a to ra?

Njẹ, a wa le ba Alukurani awọn Imale ni ori igba awọn obinrin tabi ninu ọpọn awọn oniwosi-wosi?

## NIBO NI ARẸMU ERIN WA

Jọwọ ma ṣai gba mi laye diẹ ninu iwe irohin rẹ lati bere nipa ọrẹ wa Ogbẹni Arẹmu Erin bi o ba ti ku ni tabi o wa ni aiye, nitori ọrẹ wa yi nda wa lọrun nipa ọrọ tabi itan rẹ ti o ma nfi ṣi wa leti ati oriṣiriṣi ọgbọn ati lakaye ti o ma nkọ wa. Ẹ jọwọ awa nfẹ ri ọwọ Ogbẹni wa Arẹmu Erin o.

Emi ni,
S. A. Suberu

34, Jebba Street
EBUTE-METTA

Nje mo kọ ọrọ yi si gbogbo ẹnyin ẹda Ọlọrun, ẹ gba ọrọ na yẹwo. Ẹ jọwọ mo nfẹ esi rẹ tabi idahun rẹ lati ọdọ ẹnikẹni,

Emi ni
E. A. Ayẹṣọ'ọan,

AWẸ-ỌYỌ.


# O Nwo Iko San L'ogan !




Bi idan ni VENO'S COUGH MIXTURE yi ma a wo ikọ san, a si tun ma a ko gbogbo idọti ti i ma a dun enia ni ọna-ọfun, ni aiya ati ni ẹdọ kuro, O si ti han si gbogbo aiye pe ogun iwosan ti ki i ba a ti ni fun oriṣiriṣi ikọ aiya didun ati otutu ( Coughs, Golds, Bronchitis, Catarrh, Catarrhal Asthma, Night Coughs, Children's Coughs),

Kọ tete ra igo kan, dan an wo na !

VENO'S LIGHTNING COUGH MIXTURE





## ABIYAMỌ ETI RE MELO!

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi?
Awọn arun wọn i ha ayọ ọmọ rẹ lẹnu bi?

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JEDIJEDI

ati oriṣiriṣi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra 'YARO' awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu

"YARO" ko ni meji ni gbogbo ile Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe orukọ 'YARO' ni o wa lara igo na ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun

# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi— Iṣana oriṣiriṣi (Matches), Oogun Iyagbẹ (Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Ọti Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes) Leather Shoes (oriṣiriṣi), Beer, Shnapps, Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn oriṣiriṣi ogun Ini oke Ṣọbu wa — Oogun Naruu Iba, Asun-ẹiẹ-ṣ[illegible], Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ogun fun Obinrin ati Ọkunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.

## Abiyamo! "Bamwo" De!! Alajela Omode!!!




Idẹra ati alafia de ! Ko si ibanujẹ ati aisun mọ. Angeli olutọju ọmọ rẹ ti mu ẹbun kan wa fun u lati ọrun wa "BAMWO" ni orukọ ẹbun na. O dara pupọ fun Inu-iwọ, Iso tabi Igufẹ, Iba, Igbona, Eyi, Ailesun, Ibinu-sodi ati oriṣiriṣi aisan miran ti o ma nṣe ọmọde lakoko ehin hihu. Dan Igo kan wo, iwọ yio si ri pe o dara ju eyikeyi ninu awọn ogun ti o ti nlo fun ọmọ rẹ lọ. Igo kekere 2s. 6d igo nla 4s. 6d. ẹkọ 1/-.

# The Egba Trading Aradan Stores.

144, Denton Street, 18 Denton Bridge Street, P. O. Box 2, Ebute-Metta. Phone 569. A tun wa ni New Motor Park Ogunpa Ibadan.

